# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LEJO...

VOL. XIV N0 841 LAGOS SATURDAY OCTOBER 13 — OCTOBER 19 1962 KỌBỌ MEJI (2D)


### Agan Tun Be Ni Kongo:

## Awon Ara Ilu Nle Ajoji Jade Tomo Tomo

BRAZZAVILLE, CONGO — Ogunlọgọ awọn ara ilu Nigeria ni nwọn sare wọ ọkọ oju-omi kan ti nwọn npe ni FOCH ninu ọsẹ ti o kọja lebute kan ti nwọn npe ni Point Noire nigbati awọn Alakoso Ijọba ilu Kongo fiwe sode wipe ki gbogbo ajoji ti o ba wa larin awọn palẹ wọn mọ ki nwọn kuro nilu, ẹniti o ba si kọ ti ko lọ nkan ti o ba ri ki o fiṣe ti ara rẹ.

Onirohin wa fi ye wa wipe ija ko jọ ogun ko jọ ọtẹ yi bẹ silẹ ni ilu kan ti nwọn npe ni Gabon ni papa-gbalasa ti nwọn ti nṣe ere bọlu afẹsẹ-gba ti awọn ara ilu Congo pẹlu awọn ọmọ Gabon nṣe; ija-igboro na pọ tobẹgẹ ti nwọn fi lu enia mẹsan pa bamu-bamu.

Nigbati awọn elere-bọlu ọmọ Congo paapa pa da dele nwọn rohin nkan ti nwọn fi oju awọn ri ni ilu Gabon, eleyi jẹki awọnna mu ada ati kunmọ wipe gbogbo ajoji ti [illegible] loju kan bibẹ ni aw[illegible] a bẹ wọn lori. Ọrọ wa di ọlọmọ ko mọ ọmọ. O to irinwo awọn ọmọ ilu Nigeria ti nwọn gunlẹ si ebute Apapa ni irọlẹ ijẹta. Ko si si ẹniti o duro mu ẹru ninu wọn.

### Ofin Tuntun:

## Ijoba Ghana Tun Gbe Ominran De!

ACCRA — Awọn Olotu Ijọba ilu Aganyin tun gbe wahala miran de! Nwọn ti fi iwe sọwọ si ile-iṣẹ Adele-Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lati Accra nibi wipe awọn fẹ ṣe ikilọ fun awọn ara Ipinlẹ Iwọn Orun ni Nigeia pe fofo-fofo ti nwọn npara ilu Aganyin nibi pọ ju.

(Wo yoku loju ewe kẹrin)

### Awon Oloye Eko Nlo Si Kansuln

EKO—Irohin kan wa ni ile iṣẹ wa loru ana pe nwọn ti yan awọn Oloye Eko ti yio ṣe aṣoju ni ile igbimọ Munisifa Eko tuntun ti nwọn fẹ fi idibo yan awọn aṣoju si ni ọtunla ọjọ Aje (Monday).

Orukọ awọn Oloye mẹrin ti nwọn yan na ni Oloye Ọjọra, Ajibọla Ọdunsi, Oloye Onisẹmọ, Tawaliu Bello, Oloye Eletu Odibo, Ayọ Bajulaiye ati Oloye Faji, Osenatu Gomez. On nikan na ni o jẹ obinrin ninu wọn.

Eleyi ni o si jẹ akọkọ ti Oloye obinrin yio ṣe aṣoju ara Eko lọ si ile igbimọ Munisifa.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital £3,181,000

HEAD OFFICE
82/86, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

DIRECTORS:

SAMUEL LAYIWOLA DUROSARO-Chairman/ Managing Director ABDUL AZEEZ OLAYIDE DUROSHOLA-General Manager AYOTUNDE OLATUNDE OSHINIBI

LONDON OFFICE
15,THROGMORTON AVENUE, E. C. 2.

Manager J. F. Burton.

Telephone London Wall 4303 — Cable & Telegrams Natbaniger ; London.
Head Office Representative in London.

E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS

NEW YORK PARIS HAMBURG
30 Branches Throughout Nigeria Including

IBADAN. BENNI-CITY. SAPELE. ABA. KANO. ZARIA. JOS.



RECORDS OF THE WEEK

78 RPM at 7/- each
PS2302 H
Omorere/Apollo Special
By Dr. Aramide
Apollo
Highlife
PS2532 H
Oju Totirokun/
Osu Olale
By Adebukonla Ajao
and her Group
Waka & Apala
45" RPM (Single)
at 7/6d each
B372976 F
Blueberry Hill/
Maybelle
By Johnny Hallyday
TWIST

PHILIPS
of course...
— the records of the century —
Philips (Nigeria) Ltd.
Head Office: P.M.B. 1136
Apapa.
Branch Office: P. O. Box

## Oro Pa

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

lati wo ara ati idan ti o fẹ fi awọn ejo na pa. Bi o ti nawọ sinu koto lati fa wọ n jade ni ọkan we mọ ọ lọwọ, ti o tu si i loju, o si gee jẹ.

Ọpọlọpọ awọn ti o pejọ lati woran tuka mọ ọ lori nigbati nwọn ri wipe Paul ṣubu lulẹ o njẹ oro–iku.

Ko pẹ lẹhin eyi ni baba Ologun yi ba na gbalaja silẹ ti o ku bam▪ - bamu.

Awọn babalawo ti nwọn pe si bi oku rẹ ni boya o ti dә ẹṣẹ kan ti o fi sẹ si oriṣa Ogun ni nitoripe o ti pẹ ti Ọgbẹni na ti ngbe akoto ejo rẹ sere ogun kiri arọko ilu Ibo.

## Oro Ilorin

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

### Olofintoto

Nwọn ni agboojọ ki gba ọjọ kan ti: O l o t u, mo dupẹ lọwọ yin pupọ fun alaye ti ẹ sọ wipe ki nwa lori ọ r ọ awọn Igbomina pẹlu Ilọrin ti o ti hu ọgan ohin, sugbọn ki nto ma ba iwadi mi na lọ mọ fẹ ki awọn ọkawe mi ka iwe yi ti mo ri gba lọwọ ọ k a n ninu awọn ọmọ Igbomina ti o nkọ ẹkọ nilu Oyinbo ti o pe orukọ ara rẹ ni Matthew Ọla.

Iwe ti Ogbẹni Matthew na fi ṣọwọ si wa lori ọrọ awọn Igbomina ti nwọn ni awọn nfẹ adase ijọba ibilẹ ti awọn lọtọ niyi lati agbe gbe kan ti nwọn npe ni Tottenham, London ni o ti fi sọwọ siwa:

"Alagba, ọpọlọpọ iwe irohin Eleti–Ọfẹ a t i i n u awọn ti ẹ kọ ọrọ ilu w a pẹlu awọn ara Ilọrin si ni awa na ri ka ribi. Ẹ ṣe p u p ọ; s u g b ọ n nibo ni ẹ ba wa fi ori'ọrọ na ti si ? Eyiti a gbọ g b ẹ h i n lori ọrọ adaṣe ijọba ibilẹ ti awa Igbomina sọ w i p e a nfẹ lati ọdọ ijọba i b i l ẹ Ilọrin ni alaye ti Ijọba Ipinlẹ Ariwa fi igba kan ṣe lati Kaduna lati iwọn nkan bi oṣu mẹfa wipe idibo (plebiscite) ni awọn yi... ere lọwọ gbogbo awọn ara ... lọmọde lagba eyiti nwọn ba fẹ ṣe nibẹ.

"Lati igbana lọ a ko gbọ nkankan nipa ọrọ na mọ. Awọn Yoruba sa npa l'owe wipe Ọmọ yio ku, ọmọ yio ye ni, o yẹ ki a ki abiyamọ ku ewu? Ẹnyin alagba o yẹ ki ẹ sọ ọrọ na si etigbọ wa bi gbogbo rẹ ba ti nlọ si tabi awọn alamojuto Ijọba ti fi ofin de nyin mọ'lẹ wipe ẹ ko gbọdọ fẹnu kan ọrọ na rara mọ ni?

"A fi igba kan gbọ wipe awọn kan lati ilu Ilọrin ngbe iwe kakiri igberiko lọdọ awọn ijoye agbegbe Ọffa, Igbomina ati bẹẹbẹ wipe ki nwọn fi ọwọ si iwe pe awọn ko lẹnu ninu ọrọ ki nwọn ya adase ijọb ibilẹ fun awọn ọmọ Igbomina. Bi otitọ ni eleyi, irọ ni, a ko ri ẹnikan sọ s

"A tun fi igba kan gbọ ọrọ ko-jọ'rọ-ko-jo'tọ kan wipe gbogbo iwe-ẹbẹ ati alaye ti wọn nkọ ṣọwọ si Ijọba Ipinlẹ Ariwa nipa ọrọ na ko de Jẹbba ki a to wipe o de Kaduna. Nwọn ni oke ile Ajẹlẹ ni awọn iwe nanpọra si.

"Ẹ jọwọ alagba, a fi ipọri alajọbi bẹ nyin ki ẹ ba wa wa irohin ti o kun lori ọrọ na.

Emi n/,
Matthew Ọla??."

Bi Olofintoto ti wa idi ọrọ ilu awọn ara Ilorin ati awọn ọmọ Igbomina na si ẹ o ma gbọ iyoku ninu ọsẹ ti mbọ.

**AKIYESI:** Tete sọ fun ẹniti o nta iwe irohin fun ọ ki o fi iwe "Eleti–Ọfẹ" tirẹ pamọ fun ọ. OLOFINTOTO "Eleti–Ọfẹ" yio sọ pato lọri ọrọ awọn ara Ilọrin pẹlu awọn ọmọ Igbomina.


IBI IJOKO AWAMOTO INU USTIN S 200 DARA TOBE TO FI NMU ARE AWAMOTO DINKU PUPOPUPO – O NMU MOTO—WIWA RORUN PELU AISI EWU !



Mọto Austin to lagbara yi tunbọ nṣe aleknun wiwa-mọto laisi ewu nitoripe a ti ṣe e dara tobẹ, eyiti yio jẹki iṣẹ rẹ jafafa siwaju si i, ki ere si ma wọle pupọ fun ọ. Mọto S ati T 200 ni inu fifẹ, to si balẹ fun ẹru kiko; jigi iwaju rẹ lagbara, o si njẹki enia riran dada; ojuferese rẹ njẹki mọto ṣe wa fẹhinrin laisi ewu. Bere pe ki a wa a wo ki o ri i.

AUSTIN S 200

Nigeria Head Office 237 — 241 Igbosere Road. Private Mail Bag 2083, Lagos. Garages at Aba. Apapa, Benin, Ibadan, Jos, Kano, Lagos. Onitsha and Port Harcourt.

SCOA Motors




Driving any car with the three pointed star you will experience that special joy shared by Mercedes-Benz enthusiasts all over the world: The joy in perfection, in superb craftsmanship in every detail and in lasting value, in discreet elegance and in the reassuring knowledge of driving in comfort and safety at all times, anywhere.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS. IBADAN. KANO. KADUNA. JOS. ABA. PORT HARCOURT.

SUB-DISTRIBUTORS:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY. ONITSHA. ABA.

## Oro Idibo Kise Yeye

Boya ọpọlọpọ wa ko se akiyesi wipe awọn obinrin wa ki fẹ rara lati fi idi ọja wọ silẹ lojo ti nwọn ba fẹ ṣe idibo ni arin ilu Eko. Eyi ti di iwa Yoruba: ọrọ na ko ba oju mu rara.

O yẹ ki a mọ wipe ti a ko ba lọ dibo lati yan awọn ti a fẹ fi ṣe Aṣoju tiwa sibẹ ẹni ti ko fẹ ni idibo awọn ti o la dibo yio yan sibẹ, e o ma wọ ranmu.

Bi a ba nfẹ l'ọsiwaju ilu Eko ati agbegbe rẹ ki a tete lọ ju iwe-idibo wa sinu apoti idibo ni ọjọ kẹdogun oṣu yi. Ọrọ idibo kiṣe yeye lọdọ awọn obinrin ilu Ibo.

O yẹ ki awa na sọ fun awọn alejo wa wipe ọmọ ọkọ ni wa.

Ibadan St, Ebute-Metta — Emi ni, Adunọla Abati.

## Obinrin Eko E'Dibo

Olotu, ẹ jọwọ ẹ ba wa te ẹ mọ awọn obinrin wa leti wipe ki nwọn jọwọ ki nwọn tete lọ si ile-idibo ninu ọsẹ ti mbọ lati lọ dibo.

O je nkan ti o ma ni awa Yoruba ti a ti lọ se cale, ti a ti n bi awọn obinrin ilu Ibo ṣe ma nji ni owurọ kutukutu lọjọ idibo lati lọ dibo. Nwọn a tele ji kuro lori ibusun wọn, nwọn a wẹ ọmọ wọn, nwọn a si se enje fun ọkọ wọn.

Ọjọ ọdun kan ni ọjọ idibo je lọdọ awọn ara wa ni Ipinlẹ Ila Orun. Nitorina ẹnyin ọkọ, e fun awọn aya yin laye lati tete lọ dibo fun ilu Eko.

EKO — Emi ni, Tanimọwo

## Alhadji Disu Se Iranti Oku Baba Re

Irohin ko to afojubu ni ayeye iranti Ologbe Alhadji James Asani Disu ti apele oruko rẹ nje Alhadji Awaiyewaṣerere ti ọmọ rẹ Alhadji Y. Ayinla Disu (Awaiyewaṣerere Keji) ṣe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keje oṣu yi.

Alhadji Lemọmu Minirudeen Ayinla Agoro ti Mọṣalaṣi Agoro Alhadji Lemomu Abufa Ganiyu Lawal ti Mọṣalaṣi Oluwọle ati Alhadji Lemọmu Isiaka Shitu ni o ṣe akanṣe adura ni mọṣalaṣi wọn fun Ologbe na ati fun ọmọ rẹ Alhadji Awaiyewaṣere Keji. ọmọ rẹ, na si nawo fun wọn ọmọ Oku na, Sidikatu Fashola (Iya Iyabọ) si se ase fun awọn ẹbi Ologbe na. Ki Ọlọrun da awọn ọmọ oku na si.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Ojo Idibo

Otunla ọjọ Aje ni ọjọdibo ni Eko bi awọn ALAGBARA ko ba fi iwe-agbara naa duro. Awọn alagbara pọ ni aiye ti a wa ni ode isisiyi. Agbara Ọlọpa, agbara sọja, agbara adajọ ati ti awọn Minisita alamojuto iṣẹ Ijọba ni orişirişi. Awọn alagbara kan ti o tun wa nisisiyi ti nwọn kẹ ṣe fi ọwọ rọ sẹhin ni awọn OBINRIN. Ọrọ obinrin toto-toto. Bi nkankan ba nle obinrin ni wa ba nibẹ, nkankan ba tun nrọ awọn iya wa ni wa ba nibẹ.

## Obinrin Hoteli

Ọrọ awọn obinrin kanpa tobẹgẹ ti o fi je wipe awọn kansilọ ti ana ni ilu Eko ni awọn ko gbọdọ le awọn obinrin kan ti awọn ti fi s'ero wipe awọn lẹ le jade nitu lọ ti awọn yio fidibo Eko na pari nitoripe agbara mbẹ lọwọ awọn obinrin hotẹli.

• Mo gbọ wipe awọn obinrin hotẹli yi ni awọn ẹgbẹ oselu kan gbojule ni pataki ni Yaba, Ọbalende, Apapa ati Abule ijẹşa fun a-ti-wọle wọn pada si ile igbimọ kekere na ti a fẹ dibo fun yi. Ọrọ obinrin to! to!! to!!!

## Kansilọ Eleyinjuege

Nwọn ni awọn obinrin kansilọ ẹlẹyinjuẹgẹ ti a o dibo fun ni ọtunla jẹ mẹrin gbako; o dara bẹ, şugbọn kilose ti awọn ọ̀na Olowogbowo kii fẹ yan awọn obinrin sita pe ki a dibo fun wọn? Bẹ wọn ni awọn ọmọbinrin ti o yanju nibẹ. Nibẹ ni Rẹmi Macaulay (ọmọ Pearse Elerin) pẹlu aburo re Titi aya Dokita Franklin wa, Ayọ (ọmọ Alufa Ajayi-Ajagbe) aya Potts-Johnson wa nlẹ ati awọn bi Ọmọlara Allen ọmọ Moore, Tayọ Macaulay ọmọ Elliott, Tọwọbọla Byass ati Bimbọla aya Lọya Silva. Bi nwọn ti pọ ninu Kiriyo bẹni nwọn pọ ninu awọn Imale ni Olowogbowo; nibo ni ẹ fi Wosilatu iyawo Alufa Ekemọde atijọ si ati Lati ọmọ Fanimokun? Ti mo ba fẹ darukọ wọn iwe a kun a-kun fa ya.

## Buredi D'orisa

Olotu Eleti-Ọfẹ eleti-ọfẹ ni nitotọ; on ni oniwe iroihin Yoruba ti o kọ gbe irohin sode wipe ọrọ fulawa (flour) fẹ mu burẹdi di Orisa kekere-a kunlẹ-bọ ni ilu Eko. Nitotọ bẹni ni o si ri.

Mo gbọ wipe l'Eko nikan kọ ni burẹdi ti di orişa kekere a-kunlẹ-bọ nitoripe awọn oniburẹdi ilu Ibadan paapa ti fi aake kọri, nwọn lọ si ọdọ babasale ẹgbẹ wọn, ọrẹ mi, Abọlade Coker ni eti Resi (Racecourse Rd) wipe awọn na ko fẹ fun ara Ibadan ni burẹdi bọlugi jẹ.

Awọn oniburẹdi Abẹokuta, Ọyọ Ibinni ati Ijẹbu Ode ni on ti o kan wọn l'Eko ni o kan awọn na. Awọn oniburẹdi ilu Kano ni ko l'ẹ gbẹ nwọn si nro nkan ti nwọn yio se lori ọrọ fulawa Apapa ti burẹdi rẹ kii dide ti nwọn ba die in tan.

## Kosoko Oba

Mo ba Oloye wa Aminu Kosọkọ yọ fun ajọdun ọdun kọkanla ti o ti o gun ori oye baba rẹ ti o se ni ijeje

Ọjọ Aiku ni Iga rẹ ti gbogbo wa mọ ni Iga Ọlọja Ereko. Gẹgẹbi mo ti sọ fun nyin laipẹ yi pe Oloye Kosọkọ ko gba gbẹrẹ, ilu gbẹdu, tabi bawo ati nwọn ti npe ni isalẹ-Eko ni o fi se ikede fun gbogbo ara adugbo ti emi Ayiluka paapa taji loju orun ti mo ngbọ:

K'a tọta fun Olori,
K'ori nmu se'bẹ;
K'a m'owo f'Oloye,
K'o ri nmu s'oye

Mo gbọ wipe awọn ẹbi Oloye na ati awọn ọrẹ rẹ duro ti i gidigidi. Ọti nlọ bi rẹrẹ, onjẹ nlọ bi arira. A fi emi Ayiluka ti nwọn ko pe sibi aşeyẹ Oloye na, boya nkan oye temi di ọla ọjọ rere.

Moronfolu okun Oye, Ajinibi ọga ogun, o duro nita Alasa-ile, Alasa-ile ko gbọdọ lọ s'oko, ko si gbọdọ lọ s'odo. Ọmọ Olowu Oduru, Owu-a-wunu pe Oloye, emi Ayiluka mbẹ lẹhin rẹ o, sugbọn ki ẹ ba wa'tọju Eko ati ile iya rẹ ni Owu ni Abẹokuta. A ki ni ile baba ki a mọ ni ti iya. Kabiyesi!

Ọrọ ajọyọ ti Oloye Kosọkọ yi jẹ ki ntun niran Oye ti o tun yi wọ ile Oye fun ọrẹ mi atijọ, Oloye Eletu Odibo, Ayọ Bajulaiye ti awọn Oloye Eko sẹsẹ un yan pẹlu awọn Oloye mẹta wipe ki nwọn ma lọ se aşoju awọn ninu ile igbimọ Munisifa Eko. Ọmọ Oye ni Eletu Odibo ni ọna mejeji ti nwọn ngba bi ema — ni ti iya na ni ti baba.

Lati igba ti mo ti nmọ wo ọrẹ mi yi ni Sekiteriat (Secretariat) ile işẹ Ikọwe Ijọba lati atijọ ni mo ti nwo wipe a de ipo awọn baba rẹ lọjọ kan

Oye a mọ ori o, Eletu Odibo! Şugbọn ki ẹ mọ gbagbe emi na o

## Ofin Tuntun:

# Ijoba Ghana Tun Gbe Ominran De!

Ninu iwe ikilọ na ti nwọn gbe jade lana, nwọn n awọn fẹ ki enikẹni ti o ba fẹ wa si ilu awọn nibi lat Ipinlẹ Iwọ Orun Nigeria wa, ki o kọ kọwe sọ si Ijọba awọn tẹlẹ bi osu kan, ki awọn le mọjiru esi ti awọn yio fun Oluwa rẹ.

Adele-Alakoso Ijọba Iwọ Orun paapa si ti gbe iwe ikilọ jade lati Ibadan lori ọrọ na. O ni enikẹni ti o ba fẹ rin irin-ajo lọ si ilu Ghana ko ba şe onişowo ni tabi akowe ile işe Ijọba ni, nwọn le kọ iwe si ile işẹ on ni Agodi Ibadan ki on le fi iwe sọwọ si ile-işẹ Minisita alamojuto nkan okere l'Eko ki nwọn le ba awọn gba iwe-aşẹ lọwọ Ijọba Ghana fun Oluwa rẹ şugọn iwe awitẹlẹ ko ni lati din ni osu kan gbako.

AKIYESI OLOTU: Iru ofin ajamọsa bayi ko ye wa si, şugbọn a şe akiyesi wipe ọpọlọpọ awọn ara Ipinlẹ Iwọ Orun, lati ilu Ikirun, Ẹdẹ, Oşhogbo, Ejigbo, Iwo ati Ogbomoşhọ ni nwọn kun ilu Aganyin; boya nitorina ni nwọn şe da ori ofin ajamọsa yi si Ipinlẹ Iwọ Orun, ko ye wa si rara.

(O bẹrẹ loju ewe kini)

# Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji (5)

## (Lati Owo Omo Abati)

### Egba Soro Sin

Gbogbo ọmọ Ẹgba ọmọ Lisabi ni oko ati ile ni o mọ wipe awa Ẹgba a ṣoro sin; Ọba wa ti a nsọ itan igbesi aiye rẹ si nma nsọ bẹ nigba gbogbo ti o ba nsọrọ ni awujọ awọn 'baba wa oṣelu, awọn Ologboni, nitoripe awọn Ologboni ni oṣelu ni ilu Abẹokuta ni aiye atijọ ki aiye na to di ti awọn ọdọmọde ilu lọkunrin ati lobinrin nisisiyi.

Tani ko mọ wipe ọrọ di Ẹgba ṣoro sin nigbati ede aiyede de s a r i n Ọba wa pẹlu awọn alamojuto Ijọba Ẹgba ti atijọ ni iwọn nkan bi adọta ọdun sẹhin ti Ọba wa na binu fi iṣẹ Aṣoju Ẹgba l'Eko silẹ ti o bẹrẹsi ṣe iṣẹ agbẹ ni Cjokoro le'i Agege.

### Ajobo

Ọba wa yi nikan kọ ni ọmọ Ẹgba pataki ti o fi iṣẹ agbẹ ṣe iṣẹ nigbati a nsọ itan rẹ yi; awọn bi Ologbe Pa Jibowu, baba Ologbe Olumuyiwa Jibowu, Adajọ agba ni Kotu-ganran; Pa J. K. Coker, ọmọ AJỌBỌ, ẹniti o ṣe ọna ti Ọba wa yi ṣe de ori oye baba rẹ. Ẹ o ma gbọ eyi ni ẹkunrẹrẹ ninu itan mi nigba miran.

Nigbana ina koko (cocoa) bẹrẹsi tan ni ilẹ wa ni Alaiyeluwa Ọba Ademọla Keji si wa ninu awọn ọmọ Ẹgba ti o gbin koko (cocoa jaburata gbogbo nkan si nlọ deede lun un. Ni Ojokoro yi ni o g b e wa ti o ti bi awọn gbajumọ ọmọbirin bi Adefẹgbe aya Oloye Sholankẹ ti t'on pẹlu ọkọ rẹ wa ni Sapọn l'Abẹokuta; ibẹ na ni o ti bi Aderẹmilẹkun aya Ọmọ'ba Adeleke Adedoyin ("Ṣeriki Tulasi") ti on pẹlu ọkọ rẹ wa ni Ibadan nisisiyi ati Adenrele iya-abiye (Nurse) ni ile awọn alabiyamọ ni Ijẹmọ ni Abẹokuta lọwọlọwọ yi. Ẹgbọn awọn ọmọ-Ọba ti a darukọ yi ti o si jẹ BẸRẸ fun gbogbo awọn ọmọ ọba yoku ni Ologbe ọmọọba A d e d o y i n aya Kamson.

### Ogun Ijemo

Nigbati Ogun Ijẹmọ yio fi bẹ silẹ ni ọdun mejidinladọta (1914) (Ladapọ Alake isisiyi) ti k u r o n i n u awọn ti o mba Ọba Gbadebọ Alake i g b a n a d a imọran nipa ọrọ ilu. Awọn Yoruba ni a l a i m ọ gun, alaimọọ tẹ ni jẹ ki iyan ni koko. Iru ọrọ bayi ni o fa ti baba arugbo ti o ku si ọwọ awọn ọlọpa Ẹgba nibiti nwọn gbe daa duro si lori ọrọ a nmu ni ṣe iṣẹ nipa.

Nigbana awọn l e b i r a onisẹ ọba ko wọpọ, nitorina awọn ọlọpa nlo aṣẹ wọn lati mu ẹnikẹni ṣe iṣẹ, bi a ge koriko kuro loju ọ n a tabi ki agba ilẹ ile-ọba tabi ọgba awọn Ọlọpa. nipa iru iwa bayi jẹki ọpọlọpọ awọn ara ilu nigbana ni ikunsinu si Ọba Gbadebọ a t i awọn alabaro rẹ. Alafia ko si si ni ilu m ọ, gbogbo rẹ w a d i ruk uruku.

Ọmọ Ẹgba ti o b a dagba diẹ nigbati nwọn ja Ogun Ijẹmọ a ma fi inu sepe fun awọn ti nwọn jẹki nwọn "rẹ awọn ara Ijẹmọ bi ẹni re'la." O t ẹ Ijẹmọ yi ko ba ti pọ tobẹ bi ko'b'a'j'ẹ ti ẹ t a n ti nwọn fi tan awọn ara Ijẹmọ lọ si ojude Ọba Gbadebọ Alake ni August 1914 wipe a w ọ n f ẹ pari ija edeayede na fun wọn nibẹ.

Ogun Jamani (German) ti akọkọ ṣẹṣẹ bẹrẹ k o ju bi ọjọ marun lọ, gbogbo ṣọja ti nwọn ti n k o lọ si Kamẹru (Cameroon) ni nwọn dapa da nigbati Ọba Gbadebọ kesi Ijọba Gẹsi wipe ki nwọn ran on lọwọ. Gbogbo oju awọn ṣọja na lo nwo Hanun - Hanun. Oyinbo Ọga awọn ṣọja ti o ba wọn wa paapa ko ni suru. Ni oke Aro ni o g u n l ẹ si ti o fi ẹro-jigi wo gbogbo ilu Abẹokuta ti o ni ki on rọ agba-ibọn si ki on tete ṣe awọn ara Abẹokuta lọṣẹ, ki on le tete pada si oju o g u n J a m a n (G e r m n a) ni Kamẹru nitoripe iyẹn ni o jẹ pataki ni oju on alara. Opẹlọpẹ Oyinbo Kọmisan na Gẹsi ti o wa ni Oke-Igbein ni Ibara lọjọna, tio ba wa bẹ ẹ wipe ki o wọ ilu. Sibẹsibẹ nibiti nwọngbe sọ wipe awọn fẹ pari ija fun wọn, ni nwọn bẹrẹ si yinbọn pa awọn ainiṣẹ.

Ija na pọ tobẹgẹ ti Ọba Gbadebọ paapa fi sa kuro ni Afin ti o salọ si ọdọ ọrẹ rẹ Padi ti anpe ni Father Coquard ninu i l e awọn Alaisan ti awọn I j ọ Ṣọsi Aguda kọ si Ilesi ni Abẹokuta nigbana. Eyi fi ara pamọ fun gbogbo awọn ara ilu ti nwọn ko fi mọ ibiti o sa gba. A w ọ n miran ni nwọn ti bẹ ori Ọba Gbadebọ ni awọn ko ṣe ri i ni ilu mọ.

(Koi ti pari)

## Olofintoto Eleti-Ofe Ni:

# Oro Ilorin Pelu Awon Igbomina Di Oro Suru

Ọpọlọpọ iwe ni a ti ri gba lati ọdọ awọn ọkawe wa lori ọrọ awọn I g b o m i n a Parapọ pẹlu Ijọba Ibilẹ Ilorin ti nwọn ni awọn nfẹ ki nwọn pin Ijọba ibilẹ fun awọn ki awọn le ri a y e mu o j u t o ilọsiwaju ilu awọn. Ati 's ọ wipe ki amọ sọ si ọrọ n a mọ ni sugbọn oporo iwe i b e r e wipe bawo ni nwọn ti fi idi ọrọ na kale si ti a nri gba lati ọdọ awọn ọkawe wa kakiri jẹ ki a sọ fun OLOFINTOTO Eleti-Ọfẹ ki o tẹsẹ bọ sokoto ki o ṣe alaye di'ẹ fun nyin nipa ọrọ awọn ọmọ Igbomina ati Ijọba Ibilẹ Ilorin ti a ni ki o ba wa wadi lati ilu bi Ilorin, Ọffa, Iludun, Esiẹ, Oke-Ọdẹ, Omupo, Eko Kaduna ati lọdọ awọn ọmọ Igbomina, t i o w a ni Oke-Okun kakiri.

(Wo iyoku loju ewe kẹfa)

### Oro Ejo Pa Baba Ologun Ni Abakaliki

ABAKALIKI — Ọgbẹni Ibo baba Ologun ti orukọ rẹ njẹ Paul Ekwueme ẹni ọdun metadilogbọn ara abule kan leti Abakaliki ni a gbọ wipe ọkan ninu awọn ejo ti o fi nsere ogun kakiri arọko bu u jẹ o si pa a bamubamu.

A gbọ wipe ki Paul ọkunrin ologun yi to pade agbako iku yi, o ru akoto ti o ko awọn ejo na si lọ sinu oja, gbogbo awọn enia si pe lelori

(Wo yoku loju ewe kẹfa(

# ELETI–OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosọko Street, Lagos. "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 468 Phone 23370.

VOL. XIV. No. 841. SATURDAY OCT. 13. - OCT. 19, 1962


## ELEYI NI IDIBO ỌMỌLUWABI

Lati bi ọdun mẹrindinlogoji ti a ti bẹrẹsi ṣe idibo lati yan awọn asoju lọ si ile igbimọ kọkọre lati tun arin ilu Eko ṣe, o dabi ẹnipe ibo ti a fẹ di (iyẹn ti ẹjọ ti o wa ni Kotu ko ba da a duro) ni ọ j ọ Aje ti ọtunla yi ni a le pe ni IDIBO ỌMỌLUWABI.

Ọna ti a le fi pe ni IDIBO ỌMỌLUWABI pọ. Ni ọna kinni, eyi ni yio kọ jẹ igba kinni ti ofin ko jẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan gbe iya odo tabi Apoti ṣuga si ita gbangba lati mọ sọ ko-ba-ikun-gbe ọrọ fun ara wọn. Eleyi ni akọkọ ti a kokorin*bu ara wa.

Ko si ọran a nkọrin wipe:

"Baba Eko di yẹyẹ,
Ẹ mọ fun lẹba mọ,
Ẹ mọ fun lọbẹ mọ,
Oju la nti fun un."

Iyẹn b: Ẹnyin agbalagba ara Eko ati ọmọ Eko ni a nkọwe wa ọsẹ yi si lati si nyin leti pe ki ẹ ronu jinlẹ lọjọ ti ẹ ba nlọ ju iwe idibo yin sinu apoti, ki ẹ si bere lọkan ara nyin bi awọn ti ẹ fẹ dibo na fun kiba ṣe niti yio l ọ jisẹ ara rẹ lọhun.

### Ko Si Ariwo

Ọpọlọpọ ni ẹ ran lọ ti o jẹ wipe iṣẹ ti ara wọn ni nwọn njẹ bi nwọn ba ti de ọhun ṣugbọn bi ọjọ idibo ba ku si dẹdẹ nwọn a mọ wọ ojule kiri, nwọn a mọ bẹ nyin wipe gbogbo nkan ti ẹ ba nfẹ ni awọn yio ṣe fun nyin bi awọn ba ti de ibẹ.

A ti ṣe akiyesi orisirisi asia awọn ẹgbẹ oṣelu ni oju-samnmọ, a si ti nri awọn ikọ awọn ti nwọn nfẹ ki a mọ pe awọn ni Kansilọ Lagbaja, Kansilọ Lakaṣegbe lọla ti nwọn nwọ ojule kakiri lati ma jẹ ara wọn lepa ẹnhin. Eyi ko nṣe nkan ajeji rara, iṣẹ idẹra ti a ba ran yin ni a fẹ ki ẹ jẹ ti ẹ ba de ọhun.

A ko fẹ aṣoju ti yio di kun ẹru o wo omi ti o ti nwọ wa lọrun; a fẹ Munisifa ti yio ja fẹfa ti yio jẹ ki ilu Eko mọ toto ti ao ri moto-bọsi wọ ni ọpọku-yọku owo lọ si ibikibi larin Eko, Suru-Lere, Yaba, Ọbalende ati Apapa.

A nfẹ awọn aṣoju ti yio sọ fun awọn-ọga ile Munisifa wipe ki nwọn fọ gọta (gutter)wa daradẹra, ki nwọn si fun wa lọja ti o ba oju mu.

Eyi ni ki ẹ gbe ṣ'ero, ki ẹ si sọ fun awọn aya nyin, ki nwọn ko lọ dibo tọmọ-tọmọ fun awọn ti o bajẹ ỌMỌLUWABI.






### Iyawo'le Ni On Yio Dibo

Gbogbo awa obinrin Eko ni a mọ wipe iṣẹ afọ-gọta ati agbalẹ ọja ni awọn Minisifa jẹ ni arin ilu, o si yẹ ki ayan awọn aṣoju kansilọ ti yio le ma ba wa ke le wọn lemọ-lemọ wipe ki nwọn ba wa ṣe iṣẹ gọta fifọ pẹlu ti ọja na daradẹra.

Nitorina, mo bẹ ẹnyin obinrin Eko, ẹnyin ti ẹni oriki (obirin bi nyin ni emi paapa) ki ẹ sa agbara nyin lati ṣe gudugudu meje ki ẹ ri wipe ọkọ nyin, ọrẹ nyin ati aladugbo nyin lọ dibo ni ọsẹ ti mbọ, ki a le yan awọn ti yio mu ilọsiwaju wa si ilu fun wa si igbimọ ki o le rọ wa lọrun.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,

Iyabọ aya Lawale

Oke—Popo,
Eko

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (OLOTU): OLA ONATADE
15 Kosoko S...